**OWE**

OKU eşinşin mu ororo ikunra olorun didun bajẹ ki o ma fi run oorun didun mọ. Bẹni were diẹ wuwo ju ọgbọn ati ọla lọ.


# Irohin Yoruba

No. 803 OCTOBER 26 — NOVEMBER 1, 1960 Kobo Meji (2D.)







# AKINTỌLA ŞI ILE IŞẸ PEPSI-COLA



Aworan yi ni tí igbati Oloye Akintọla nsọrọ nipa ile işẹ Pepsi-Cola. Oloye A. O. Adeyi, Minista Alamojuto Eto Owo ati işẹ ọwọ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun lo joko ni ọwọ ọtun,

## Mushin

**Irohin ko to afojuba ni ẹyẹ şişi Ile-Işẹ Ọti-Aladun PEPSI-COLA ti Oloye S. L. Akintọla, Gbakeji Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria şi ni Mushin ni ọjọ Abamẹta ti işẹ ọjọ kejile-logun oşu kẹwa ọdun yi.**

ESẸ ọpọlọpọ ninu awọn Minista Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, awọn Ọga Ile-işẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati awọn enia ja nkan ja nkan lati Eko, Ibadan, Abẹokuta ati Ikẹja ni o pe sibẹ şoşo pẹlu awọn ẹmẹwa Alakoso Ijọba na Oloye Akintọla si sọ wipe on dupẹ pupọ fun apọnle ti nwọn şe fun on lati şi Ile-işẹ na. Wọnyi ni ọrọ işiri ti o sọ ki o to şi ile-işẹ na:—

"Nipa akitiyan Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lati ni orişirişi Ile-işẹ ni Ipinlẹ yi ni o jẹki a da orişirişi Ile-işe silẹ ni Ipinlẹ yi, nitori bẹ e ni a şe kọ Ile-işẹ Riro ọti-aladun PEPSI-COLA sinu Igo silẹ ni Mushin lati jẹki Ipinlẹ yi kun fun işe-şişe.

"Laipẹ yi ni nwọn şi Ile Işẹ PEPSI-COLA kan ni Ibadan. Ọkẹ-mẹwa pọnun (£200,000) ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fi dokowo Ile-işẹ Pepsi-Cole ti Mushin, nwọn si fi ọkẹmẹwa pọnun (£200,000) dokowo ti Ibadan. Apapọ owo ti Ijọba fi dokowo ile işẹ mejeji jẹ ogun-ọkẹ pọnun (£400,000).

"Bi ọja na ba si nta dada, a o şi Ile-işẹ na kakiri adugbo ti o ba taja ni Ipinlẹ yi. Idasilẹ Ile-işẹ Pepsi-Cola ti Mushin yi jẹki ọpọlọpọ awọn awa-mọto, ati akọwe Ile-itaja ri işẹ şe, laisọ ti ogun-lọgọ awọn oşişẹ Ile-işẹ na.

"Ki a to şe ipinnu lati le mu Işẹ Riro ọti-aladun Pepsi-Cola wa si Ipinlẹ yi Oloye A. O. Adeyi, Minista Alamojuto Eto Işẹ-owo

(Wo oju ewe kejila)

# Awọn Abiyamọ meji bi ewele

ABẸOKUTA.

NI ọjọ Aiku ti işe ọjọ kẹdọgbọn oşu kẹsan ọdun yi ni awọn abiyamọ meji kan bi awọn ewele ọmọ meji ni Ile-iwosan Ijọba ni Abẹokuta.

Apolukun ati ọwọ ọkan ninu awọn ọmọ ewele na wa ni aiya rẹ; ni apa ọtun ori rẹ ni awọn oju keji si wa.

Nigbati o di wakati mẹrindinlogoji ti nwọn ti bi ewele akọkọ ni o si ku, ekeji si ku laipẹ ti nwọn bi i.

# Ogiri wo lu t'ọkọ t'aya Ọkọ ku, aya wa ni ile-iwosan

ILỌRIN.

NI ọjọ Işẹgun ti işe ọjọ kẹrin oşu yi ni ariwo ta ge e nigbati ogiri wo lu t'ọkọ t'aya ninu yara ti nwọn sun si ni adugbo kan ni Ilọrin ti nwọn npe ni "GAMBARI".

Ọkọ ku, iyawo koi ti ku şugbọn ogiri şẹ e ni ibadi, bi o si ti bẹrẹsi ja raparapa nilẹ, ti o si nke irora ni awọn ẹbi rẹ ba yara gbe e lọ si Ile-iwosan fun itọju.

Nwọn si lọ gbe ọkọ rẹ sin.

## Atọka

**Wo**


Itumọ Ala Awọn Onibere P.4

Akibu Alarape P.9

# Irohin Yoruba
## ORO OLOTU

## Nwọn nṣ'afita-fita ni

YORUBA ni i ma a pa a lowe pe: Ijapa nwọn gba ẹ lobirin o ko ṣ'afita-fita, ni Ijapa ba lọ si ile ọkọlokoji rẹ, o si yọju si ọdẹdẹ ibẹ, o ni afita-fita o! afitafita o!! afitafita o!!!, ni Ijapa bẹrẹsi rohin kiri pe on ti lọ si ile ẹniti o gba on l'obirin na, on si ti lọ ṣe afita-fita.

AWỌN ti owe yi mba wi ni awọn aṣiwaju Aṣoju Igbimọ Ibilẹ Ilesha ti Ijọba tuka laipẹ nipa orikunkun pe awọn nfẹ ki Ọba Alaiyeluwa Ogunmokun, Biladu Kẹta, Ọwa Ilesha kuro lori oye ọba fun awọn ki awọn le ri aye lo ifẹ wọn lori ara ilu gẹgẹbi nwọn ti nfẹ, ti Ijọba si kilọ fun wọn wipe, aṣẹ wọn ko yọ ọba ti ilu ba nfẹ loye, ti ko si ṣe ohun ti o lodi si aye rẹ.

ṢUGBỌN nwọn ṣe orikunkun pe, ohun ti awọn ba fẹ ni awọn le ṣe, nwọn ro pe nitori ti awọn jẹ Alakoso Igbimọ Ibilẹ Ilesha "awọn le pa awọn si le sọ di aaye" bi awọn ba ti fẹ. Nwọn ti gbagbe pe, oye-aṣoju Igbimọ ilu ki iṣe oye idile, nwọn dibo yan wọn sibẹ pe ki nwọn ba ṣwọn tun ilu ṣe ni, bi nwọn ko ba si-rin ni l'eto Ijọba le ta wọn ka.

Afita-fita ti nwọn tun ṣe laipẹ yi ni pe nwọn pe Ijọba lẹjọ pe, ki iṣe ẹtọ Ijọba lati tu awọn ka, ẹjọ na si wa ni Kọtu nisisiyi, ṣugbọn a ri i pe "eke ni o ku nibẹ, ẹniti a bẹ lori ti o tun ngyinmu". Bi ẹjọ yio ba ku yio ṣa jowere, owere na ni nwọn nja yi, ibiti yio ba si pari si a o ma a ri i.

ONI-PASLM ni: "Ẹ nṣe fefe ninu iwa ika ẹnyin alagbara ọkunrin". Bi ko ba jẹ bẹ ẹ ni, kini i ba tun mu wọn lọ pe Ijọba lẹjọ, nigbati Ijọba ti wọn lọwọ iwa aitọ ti nwọn fẹ hu si Ọba wọn, ti nwọn si ri i pe, ko si ninu ifẹ awọn Ijoye afọbajẹ ati ara ilu lati ti wọn lẹhin, bikoṣe pe awọn Ijoye na ati awọn ara ilu nke pe Ijọba pe, ki wọn gba awọn kalọ lọwọ aṣẹonikumọ ti Igbimọ Ibilẹ Ilesha na pa.

# Iwe si Olotu Irohin Yoruba

## Ẹ FUN ỌMỌ NYIN NI ẸKỌ

BI obi kan ko ba ri aye to lati bojuto ọmọ rẹ daradara nipa ẹkọ ile ati ẹkọ iwe, ki o maṣe jafara rara lati fi i si ọdọ alagbatọ atata ti yio ma a ba bojuto dada. Ki obi na si maṣe fi owo agbatọ jafara lati ma a san.

Bi ọmọde ti o nṣe algbọran ti ko si fi oju si ẹkọ rẹ ko ba ri alabojuto atata laseko, apa ko ni ka a mọ ti o ba ti dagba diẹ, yio si di jagidijagan enia.

Ẹkọ ile ati ẹkọ iwe dara ju wura ati fadaka lọ. Ọmọ ti o ba ni ẹkọ yio wulo fun ara rẹ, obi rẹ ẹbi rẹ ati ilu rẹ.

Emi ni,
Y. AYINLA DISU.
Eko.

## Ilu Inisha nfẹ nọmba

INU mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye lati kesi awọn alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Inisha pe, ki nwọn lọwọ ba wa fi nọmba si ara ile wa. Bi o ba si ṣe pe lati ọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni aṣẹ yio ti wa ni, a bẹ Ijọba Ibilẹ na lati ba wa kesi wọn.

Olotu mo dupẹ o, ẹ ko ni ṣe e ti o.

Emi ni,
JOHN ADEGBITẸ.
Inisha.

## Mo ki Akande

YIO dun mọ mi ninu pupọ bi Olotu ba le gba mi laye lati kan saara si Evangelist J. J. Akande fun ọrọ Ọlọrun ti o ma a nsọ sinu iwe "Irohin Yoruba" ni ọsẹ-ọsẹ. Oluwa ko ni pa ọgbọn ati laakaye Evangelist Akande na rẹ.

Emi ni,
S. M. BALOGUN.
Isanlu-Makutu.

AIYE Ominira ni awa yi, idẹra ati alafia ni gbogbo ilu nfẹ, eyi si ni ireti ti gbogbo awọn enia Naijiria nreti lati ọdọ Apapọ Ijọba Naijiria, ati lati ọdọ awọn Igbimọ Ijọba Ipinlẹ ati lati ọdọ awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ ilu gbogbo. Nitorina a bẹ gbogbo ẹnyin alaṣẹ Igbimọ Ijọba gbogbo ti o wa ni Naijiria ki ẹ ma a jepa iwọnyi ninu gbogbo eto iṣelu nyin.

## Iganna nfẹ Ọba

O JẸ ohun abuku ati itiju lati ri i wipe ko si Ọba ni ilu Iganna Lati igbati ọba ti o jẹ ti waja nwọn koi ti jẹ omiran, nitorina a bẹ awọn afọbajẹ ati awọn Oloye ilu Iganna lati le tete ṣe aṣaro lati yan ọmọọba ti o yẹ s'ori oye ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun si ba wa fi ọwọ si i.

Ẹṣe o.

Emi ni,
S. A. IROKO.
Iseyin.

## Ran awọn eree lọwọ Da ẹhin didun duro

Ara rẹ nwẹ omi-aisan, kokoroarun ati panti oloro jade kuro ninu ẹjẹ rẹ lati inu adọta-lenirinwo-okẹ iho krekeeke tabi awọn asẹ ti o wa ninu Eree (kidney) rẹ. Bi awọn ọrọ ti o wa ninu awọn Eree (kidney) tabi Apo-itọ rẹ ba nfi ipa jẹ ọ nipa itọ ito rukurudu, "TI O SI NTAJI LORU LORU TI LAKURẸGBE nro ọ lẹnu, ti bebe lalẹoju rẹ ba wula, ẹhin didun ti gbogbo Iṣẹpọ ara ba nro ọ tabi ti ito ba njo ọ nidi, bẹrẹ si i ran Eree ina rẹ lọwọ nipa lilo CYSTEX loni. CYSTEX a ma a bẹrẹsi iṣẹ lẹhin wakati mẹta kiakia ni yio si wo gbogbo irora rẹ san ti yio si mu ọ lara da. a ṣeleri lati da owo rẹ pada ti ko ba ri bẹ ẹ. Ra apọgun rẹ lere.

**Cystex**
fun Eree (kidney), Ile-ito.
CYSTEX loni Lakuregbe,

## Titi Igede ko dara

TITI ọna Igede lọ si Ekiti ko dara rara, bẹ si ni a si nfẹ ẹrọ-redio lati ba a le ni anfani ati ma a gbọ irohin awọn nkan ti nlọ ni okeere. Nitorina a bẹ Ijọba Ibilẹ Igede lati ṣe awọn nkan wọnyi fun wa. Ti ko ba si ni agbara lati ṣe awọn nkan wọnyi, a bẹ wọn ki nwọn kesin Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ki nwọn ba wọn ṣe e.

Emi ni,
S. A. ỌSHATUNBERU.
Ile-Ifẹ.

## Mo gbadun Alarape

MO gbadun itan aladidun ti Ọgbẹni Akibu Alarape nsọ sinu iwe "Irohin Yoruba". Itan na nkọ ni lọgbọn, o si tun nkọ ni ni ẹkọ pe, ko dara ki a ma a fi buburu gba ẹsan rere. Oluwa ko ni pa ọgbọn ati laakaye rẹ rẹ.

Olotu mo dupẹ o, ẹ ko ni ri ija ọmọ araiye o.

Emi ni,
DAVID ADENIRAN.
Ilesha.

## Titi Okeho nfe oda

AWA ara Okeho bẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lati ba wa da ọda si ori titi wa ni Okeho nitori erukuru ọna na nko ọpọlọpọ aisan ba wa. A dupẹ bi Ijọba ba le ṣe e fun wa.

Emi ni,
B. OGUNGBE.
Ejio.



# Awọn ẹgbẹ Ṣọọsi Owu ṣẹyẹ fun Ademuyiwa



AWỌN Ẹgbẹ "African Church" Ago Owu, Abẹokuta ti o wa ni Eko ṣ'ẹyẹ fun Ọgbẹni J. A. Ademuyiwa, Olori wọn laipẹ yi ninu ọgba Ile-iwe "African Church Cathedral (Bethel)' l'Eko fun ti aye isinmi ifẹhinti kuro lẹnu iṣẹ patapata (pension) ti o gba labẹ iṣẹ Ijọba gẹgẹbi ọga-agbowo-ori (Tax Officer).

Ẹniti o fi adura si ipade aṣeyẹ na ni Ẹni-ọwọ Archdeacon O. N. Ironbar ti iṣe Alamojuto Ijọ "African Church Cathedral (Bethel)". Awọn ẹgbẹ na si fun Ọgbẹni Ademuyiwa ni Iwe-ayẹsi ikini-kuorire ti o kun fun ọpọlọpọ ọrọ iṣiri. Ẹniti o ka Iwe-ayẹsi na ni Ọgbẹni S. O. Ẹkẹade. Iyawo rẹ Iyaafin J. I. Ẹkẹade lo si fi iwe na le Ọgbẹni Ademuyiwa lọwọ l'oruko ẹgbẹ.

Lẹhin eyi ni nwọn bẹrẹ si fi orisirisi onjẹ ati orisirisi ọti ṣe igbadun aṣeyẹ na, nwọn si ya aworan Diẹ ninu awọn alabaṣẹyẹ ati awọn ọmọ-ẹgbẹ na ni awọn Ọgbẹni S. M. Ademuyiwa, Olotu Iwe Irohin Yoruba; E. A. Jọda, S. A. Fanẹyẹ, Akọwe-ẹgbẹ; S. A. Olurebi, Akọwe-owo-ẹgbẹ; S. M. Ọshunrinde, Alamojuto alafia ẹgbẹ; E. A. Famuyiwa, Akapo; I. O. Ẹgbẹtokun (Ajẹri-iwe owo ẹgbẹ) ati E. F. Faluade pẹlu awọn Iyaafin Ọshunrinde, Jibowu ati Adedọja Ademuyiwa.

Nwọn si fi adura Ore-ọfẹ Oluwa pari aṣeyẹ na.




Ilokulo ni iwọ yio ma a lo epo-mọto nigbakigba ti o ba si ẹnjinni mọto bi awọn ẹrọ iṣana mọto rẹ ba ṣalailagbara tabi ti nwọn ko ba dara. Fi awọn CHAMPION si i, iwọ yio si tete din inawo epo-mọto ku lẹsẹkẹsẹ—nitoripe awọn iṣana epo-mọto CHAMPION ntete gbina lasiko.

**CHAMPION**

*ndaabobo mejeji*

**Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun**



# Ẹgbẹ ajumọṣe Iwọ-Orun

AWỌN ọmọ Ẹgbẹ Oniṣowo Ajumọṣepọ ti Ipinlẹ Iwọ-Orun ("Co-operative Union of Western Nigeria, Ltd") ti ṣe eto nipa ipade ajọdun kẹrin ẹgbẹ na ti nwọn fẹ ṣe ni Ibadan ni



OLUBADAN IBADAN

* * *

oṣu kọkanla ọdun yi. Ipade na yio bẹrẹ ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ keji oṣu kọkanla na titi di ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu kanna.

Awọn ikọ lati gbogbo Ipinlẹ Iwọ-Orun ti yio wa si ipade ajọdun kẹrin na yio le ni ẹgbẹrun (1,000) enia.

Oba Alaiyeluwa I. B. Akinyẹle, Olubadan Ibadan, Oloye A. O. Adeyi, Minista Alamojuto Iṣẹ ati Owo Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Oloye G. Akin Dẹkọ, Minista Alamojuto Iṣẹ-Ọgbin ati Ohun Iṣura Ilẹ

FW 24



**Awon aran so o di alailagbara ati olokunrun**

Bewo ni o se le lagbara ki ozi ni alafia bi awon ara inu re ba nfi onje ti e ngbemi je? Nwon ntobi si i bi iwo ti nru si i: Ohun kansoso ni o le se: Awon Dokita mo wipe o nilati le awon aran kuro ninu re nipa lilo egbogi pataki.

Egbogi aran **DE WITT'S Worm Syrup**

Ole ra egbogi aran De Witt's Worm Syrup nisiyi lati fi se ise na kiakia: Pelu igo kookan, wa a ri alaye kikun—funra ara re tabi awon omo re. Egbogi aran De Witt's Worm Syrup yio dun dada lenu re, sugbon nkan buruku ni fun awon aran: Egbogi alagbara yi yio da gbogbo awon aran ni ijakadi yio si le won kuro ni ara re kiakia. Nitorina ra egbogi aran De Witt's Worm Syrup nisisiyi, wa a si tete beresi ni alafia ati ara lile, wa a lagbara okan re yio si tun bale.






# onişowo pọ Ipinlẹ un yio şe ipade nla

Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun yio ba ipade na sọrọ ti o tọ ti o si yẹ.

Oloye S. L. Akintọla, Gbakeji Olori Egbẹ Afenifẹre ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun yio ba awọn ikọ na sọrọ ti yio şe wọn ni anfani pupọ ni ibi apejẹ ti ẹgbẹ na yio şe fun awọn ikọ na ni ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ kẹta oşu kọkanla ọdun yi.



OLOYE AKIN DẸKỌ

Minista Alamojuto Eto Ohun Ogbin ati Ohun Işura ilẹ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun


## WO IKỌ FEE SAN

### Sun un bi ọmọde

Bi o ba nwukọ ti o si nsin, ti o ko si le mi kan'lẹ tabi ti o ko le sun dada nitori ikọ-fee, Amodi-'mu tabi otutu igb'aiya, ra MENDACO l'owọ onişegun rẹ tabi ile-itaja l'oni. Ninu ẹjẹ ati iho keekeeke inu ẹdọ-foro ni MENDACO ngba sişẹ, yio si yọ ẹjẹ ti o ti di yio si ti i idọti ibẹ jade. Nigbayi ni ikọ rẹ yio san, wa a le mi dada, wa a si le sun bi ọmọ-ọwọ, wa a si ni agbara ọtun pada.

A ni igbẹkẹle si i, nibẹkọ, a o da owo rẹ pada.


# Awọn Ẹgbẹ Nawair-un-Deen şe ajọdun ni Funtua



NI ọjọ kẹta oşu kẹsan ọdun yi ni ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Nawair-ud-Deen ẹka Funtua pe si ile alaga wọn, Ọgbẹni R. A. Allara lati şe ajẹyọ ọjọ ibi Anabi Mohammed. Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni nwọn şe ẹşọ alarinrin ti gbogbo ẹnikẹni si gbadun wọn.

Alaga ajọdun na ni Alagba Sanni Laboye, onişowo ekurọ ni ile-işẹ awọn Onişowo Fransẹ (CFAO). Iyaafin Ajikẹ Fọlọrunşọ ni alaga obirin.

Ki işe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni nwọn wa şe ajọdun yi, işe gbe ẹlomiran lọ si arọko, ẹlomiran si lọ si isinmi ninu wọn. Şugbọn awọn ti nwọn wa nilu şe ajọdun na, gbogbo eto wọn si gun geregere

Aworan yi ni ti igbati nwọn pesẹ lati bẹre ajọdun na. Awọn ti nwọn joko lati ọwọ osi ni: Ọgbẹni L. Lawal, R. A. Adamu, Bello Ọpatoye, Alfa Lamidi Awaye, Alaga R A. Allara, Ọgbẹni Ashinmi Ọlaiya ati Ahmed Bakare. Awọn ti nwọn duro lati ọwọ osi ni Ọgbẹni S. Suberu, Busari, Ladeji, Saibu Arowoşẹgbẹ, L. J. Oke, D C O Bank, S. Ade Barber, Alfa Wahabi Adisa ati G. A. Bankọle.

Ọlọrun jẹ ki a şe ọpọ ọdun laiye ẹ.





Ni ikẹhin— IWOSAN FUN RORẸ ATI OORU-ARA-SISU

Nisisiyi, awọ-ara rẹ yio mọ gara yio si jọlọ pada! Ni ikẹhin, egbogi kan niyi ti o le wo gbogbo rorọ ati ooru-ara-sisu san patapata.



Egbogi Agbarun

VINOLIA

IYẸFUN EGBOGI RORẸ ATI OORU-ARA-SISU

– ti awọn Dọkita nlo

VINOLIA ROBUN PUPỌ LATI LO PẸLU

Lẹhin ti o ba ti fi ọşẹ ati omi wẹ ara tan, fi ọpọlọpọ iyẹfun egbogi na kun ibiti o ba ndun ọ ni ara rẹ dada. Lo iyẹfun na bi o ti wu ki o ri lẹkan lọsan ati lẹkan lalẹ. Ni ọjọ kini, kikan rẹ yio rọle, ni ọjọ keji, awọn rorẹ yio gbẹju, ati ni ọjọ kẹta ati ẹkẹrin gbogbo wọn yio jinna nwọn yio si parẹ.



Iyẹfun egbogi Vinolia fun ooru-ara-sisu ni iyatọ diẹ ni ara si iyẹfun egbogi agbarun lasan, şugbọn idi eyi ni pe, nitoripe oogun egbogi ni.

BIBELI MIMỌ T'ỌRUN
ỌWỌN IṢURA T'EMI

# Ominira Ilẹ Naijiria [2]

**(Lati ọwọ Evangelist J. J. Akande**

ESẸ wura alaye keji ti a o ṣe nipa ti ominira Ilẹ wa, ni ọrọ ti a sọ ninu Orin Dafidi ori 118, ẹsẹ 24, bayi pe, "Eyi li ọjọ ti Oluwa da, awa yio ma a yọ, inu wa yio si ma a dun ninu rẹ."

Idi rẹ ti o fi yẹ ki inu gbogbo awa ọmọ Naijiria ki o dun, ki o si fi ọpẹ fun Ọlọrun ni pe, bi o ba jẹ pe awọn orilẹ-ede kan lo wa gbogun ti wa lakoko yi, ti nwọn ṣẹgun ilẹ wa ni, gbogbo wa ni a ba ni ipin ninu ijiya igbekun na, ṣugbọn ọrọ tiwa ki iṣe ti igbekun bikoṣe OMINIRA, eyiti iṣe ẹbun Ọlọrun.

Apẹrẹ ominira ni akoko ti Jesu Kristi wa si aiye yi, o wa ki araiye le ni ominira, gẹgẹ bi a ti ri i ka ninu John ori 1, ẹsẹ 17, bayi pe, "Nitoripe nipasẹ Mose li ati fi ofin funni, ṣugbọn ore-ọfẹ ati otitọ tipasẹ Jesu Kristi wa."

**MAJẸMU LAILAI**

Ninu Majẹmu Lailai, nigbati awọn enia wa labẹ ofin Mose, inira lo jẹ fun wọn, ofin tulasi ni nwọn nlo, ko si aye idariji fun wọn lakoko na, apẹrẹ aṣẹ ti nwọn nlo larin ara wọn nigbana ni eyiti a ri ka ninu Eksodu ori 21, ẹsẹ 24, bayi pe, "Fi oju dipo oju, ehin dipo ehin, ọwọ dipo ọwọ, ati ẹsẹ dipo ẹsẹ." Eyi fihan pe ko si aye idariji rara fun wọn nigbana.

Ṣugbọn nigbati Jesu de, nigbana ni ominira de, ti anu si de, ti idariji si de pẹlu. Nitorina ni Jesu fi sọ ninu Matteu ori 9 ẹsẹ 13, bayi pe, "Anu li emi nfẹ, ki iṣe ẹbọ, emi ko wa lati pe awọn olododo, bikoṣe awọn ẹlẹṣẹ si ironupiwada."

Ati eyiti o tun sọ ninu Matteu ori 5 ẹsẹ 43-45, bayi pe, "Ẹnyin gbọ bi a ti wi pe, 'Iwọ fẹ ọmọnikeji rẹ, ki iwọ si korira ọta rẹ, ṣugbọn emi wi fun nyin, ẹ fẹ awọn ọta nyin, ẹ sure fun awọn ẹniti o nfi nyin re, ẹ sure fun awọn ti o korira nyin, ki ẹnyin ki o le ma a jẹ ọmọ Baba nyin ti mbẹ li ọrun, nitoriti o ngmu orun Rẹ ran sara enia buburu ati sara enia rere, o si nrọjo fun awọn olotọ ati fun awọn alaiṣotọ."

**ISIN JESU KRISTI**

Nigbati isin Jesu Kristi de aiye, nigbati ẹsin na bẹrẹsi gbilẹ si i, nigbana ni ifọkanbalẹ de ba enia, ti alafia si npọ si i larin ilu kan si ekeji. Ilu tabi orilẹ-ede ti ẹ ba gbọ pe nwon nhuwa jagidijagan ati ipania, dajudaju ki iṣe isin Kristi lo gbilẹ ninu iru ilu bẹ ẹ, ilu ti isin Kristi ba ti gbilẹ, ẹ o ri i pe ilu na yio ni alafia, yio si laju ju ilu miran lọ.

Nigbati Isin Kristi de ilẹ wa, nigbana ni ogun jija ...n, nigbana ni ara Ọyọ to le rin kọja larin ilẹ Ijẹsha, nigbana ni awọn Ẹgbẹ sinmi ogun jija pẹlu awọn Idahọmi, nigbana ni nwọn ko tun ko enia dudu l'ẹru lọ si oko ireke awọn Amẹrika mọ, dajudaju, nitori ominira awa enia ni Jesu Kristi fi wa si aiye yi.

**IGBALA FUN WA**

Otitọ ni ọrọ ti a sọ nipasẹ Jesu ninu Isaiah 42: 7, bayi pe, "Lati la oju awọn afọju, lati mu awọn onde kuro ninu tubu, ati



Evangelist J. J. Akandẹ

* * *

awọn ti o joko li okunkun kuro ni ile tubu." Nitorina, nigbati Jesu de aiye yi, o fi gbogbo igbesi aiye Rẹ ṣe iṣẹ idande ati igbala fun awa enia, ti o si jẹ imọlẹ fun araiye, gẹgẹbi on na ti sọ ninu John 8: 12, bayi pe, "Emi ni imọlẹ aiye, ẹniti o ba tọ mi lẹhin ki yio rin ninu okunkun, ṣugbọn yio ni imọlẹ iye.'

Imọlẹ na lo la gbogbo wa loju titi a fi ri ọna ominira ti a gba yi, Imọlẹ na lo sọ wa di alagbara gẹgẹ bi a ti wa loni yi, ti awa na fi di enia pataki ninu ominira. Ki Ọlọrun ki o ṣe ominira na ni itura fun gbogbo wa. Amin.




# Ọmọ marundiladọrin lo wa nile ẹkọ awọn aditi

OGBENI Andrew Foster, Alakoso ile-iwe awọn aditi ati odi ni Ibadan Ibadan Mission School for the deaf) ṣe ikede ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kini oṣu yi pe ile-iwe na nfẹ iranlọwọ gbogbo awọn ara Naijiria fun ilọsiwaju iṣẹ ẹkọ ti ile iwe na nṣe. Ọgbẹni Foster sọ pe awọn nfẹ iranlọwọ lati isisiyi lọ titi ọdun yi yo fi pari.

O ni ile-iwe na nṣe iṣẹ ribiribi fun awọn ọmọde aditi, o si tun sọ pe iranlọwọ owo ti awọn mbere fun yio ṣe awọn ọmọ na ni anfani, nitoripe iṣẹ na gbooro si i ni. O ni awọn ọmọ marundinladọdin (65) ni o nje anfani ẹkọ ninu ile-iwe yi, ati pe opolopo ni o si wa nita ti koi ti si aye fun lati ma a kọ ẹkọ.

Ọgbẹni Foster ni awọn obi ọmọ wọnyi ki nsan owo fun ẹkọ ti awọn ọmọ wọn nri ni ile-iwe yi, o si ni iranlọwọ owo ti awọn nwa yi yio tubọ jẹki awọn o kọ awọn enia ti nwọn yio tun jẹ olukọni ni ile-iwe na. O ni ọpọlọpọ nkan ti o wulo ni awọn nfẹ ra fun ilọsiwaju ẹkọ awọn ọmọ aditi wọnyi, eyiti lilo wọn yio ṣe nwọn ni anfani ti nwọn yio fi jẹ ọmọ-atata fun ilu wọn.

Ọgbẹni Foster jẹ ara ilu Amẹrika. Aditi ni on na, ṣugbọn ọmọ'we gidi ni.

## ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN

# Ori l'o mọ'ṣẹ aṣela ẹni (3)

OLOTU Iwe "Irohin Yoruba", ajinde-ara yio ma a jẹ [illegible] ọrọ wa atẹhinwa, mo ro wipe gbogbo ẹnyin onkawe wa na ni yio ti ranti ibiti a ba ọrọ wa na de?

Laifa ọrọ gun lọ titi, ọmọdekunrin na si mba ọrọ rẹ lọ bayi wipe: "Ẹnikeji mi ti a jijọ wa si ilu yi lati ilu wa jẹ ẹnikan ti o ni ẹkọ iwe daradara, ṣugbọn emi ko mọ iwe de a.

"Bakannasi wẹ, mo si tun kọ ẹkọ nipa orişirişi iṣẹ ọwọ, ṣugbọn bakanna [illegible] alairiṣẹ ṣe. eyi na si ni nkan pataki ti o ṣẹlẹ ni ilu wa lọhun ti mo fi ro wipe nkan na le rọrun diẹ bi a ba wa si ilu yi.

### IRANLỌWỌ ALFA

Nigbati ọmọdekunrin yi pari ọrọ rẹ tan bayi, Alfa na wa tun bere wipe "Njẹ, iwọ yio le ba mi kalọ sile bayi? nitoripe Alfa pataki ni mo jẹ ni ilu yi, to bẹ ẹ, ti o fi jẹ wipe ko si Alfa kan ti o ni imọ ju mi lọ ni ilu wa yi.

"Iranlọwọ ti mo si le ṣe fun ọ bi a ba dele ni pe, mo fẹ ṣe ayẹwo si ọrọ rẹ, nipa bayi, emi yio le sọ fun ọ, bawo ni igbesi-aiye rẹ yio ti ri, atipe iru ọna ti iwọ yio gba di enia nla"

Bayi ni awọn mejeji pari ọrọ na si, nwọn si jijọ nlọ si ile Alfa. Nigbati nwọn dele tan, Alfa gbe ọpọn yanrin rẹ kala. Lẹhin ti Alfa yi tẹ yanrin na silẹ tan ni nkan bi ogun iṣeju, nigbana ni Alfa yi bere lọwọ ọmọ na wipe: "Njẹ, iwọ mọ baba rẹ [illegible]ba bayi?" ọmọ na si dahun wipe: "Baba mi agba ti ku nigba ti mo wa ni kekere, oju mi ko si da si ara baba na tobẹ ẹ, ṣugbọn baba ti o bi mi si wa laiye bayi pẹlu iya mi bakanna".

### ỌMỌ DAHUN PE

Alfa na si tun bere pe: "Njẹ iwọ mọ iru iṣẹ ti baba na nṣe ni igba aiye rẹ bayi?" Ọmọ na si dahun wipe: "Emi ko mọ eyini rara; ṣugbọn iṣẹ ti baba ti o bi mi nṣe ni owo malu, to bẹ ẹ, ti o fi jẹ wipe o fere ma si ẹniti o ni owo bi baba mi ninu ilu wa'.

Alfa na si sọ wipe: "ko buru, ṣugbọn nisisiyi, 'gbati mo ṣe ayẹwo ọrọ rẹ finni-finnin, mo ri i wipe ninu gbogbo iṣẹ ti o wa lode aiye yi, iṣẹ kanṣoṣo na ni mo ri fun ọ, ti o le [illegible]

[illegible] ṣugbọn ẹru si mba mi boya iwọ ko ni le ṣe iṣẹ na, ṣugbọn eyiti o kan mi ni wipe, emi ko gbọdọ ma sọ ododo [illegible] o tilẹ jẹ wipe ọpọlọpọ ọmọ enia ni ko nfẹ gbọ ododo ọrọ'.

Lori ibiti Alfa yi ti mba ọrọ rẹ na lọ lai ti i dakẹ lẹnu, lẹsẹkẹsẹ na ni ọmọ yi ti gba ọrọ lẹnu rẹ, ti o si bẹrẹsi iwa-nwara sọrọ wipe: 'Họwu, kiniṣe ti emi ko ni le gba ododo ọrọ gbọ, nigbati o jẹ wipe mọ jẹ ẹniti ko fẹran irọ pipa lati igba ewe mi wa? Atipe bakanna si wẹ, kini ṣe ti emi yio fi sọ wipe iṣẹ kan wa ti emi ko ni le ṣe nigbati o ṣe wipe airiṣẹ nkankan ṣe na ni o mu mi wa si ilu yi, ti o si jẹ wipe ọjọ ti a de ilu yi gan an ni ekeji mi ti a jijọ wa si ti ri iṣẹ ṣe, ti emi ko si ti i ri iṣẹ kan ṣe titi ti o fi di isisiyi?



AKIBU ALARAPE

★ ★ ★

"Nitorina, mo fẹ ki ẹ sọ ododo ọrọ fun mi, ara mi yio gba a. Atipe, mo si tun fẹ ki ẹ mọ daju wipe ko si iṣẹ ti nko le ṣe o. a fi ole nikan ni nko le ja, nitoripe lati igba ewe mi ni baba mi pẹlu iya mi ti ma a nkilọ fun wa wipe, awa ko gbọdọ jale, a ko si gbọdọ purọ, bayowu ki nkan na le le to.'

### KO SI IṢẸ MIRAN

Nigbati ọmọ yi sọ gbogbo ọrọ rẹ dele tan ni Alfa na wa dahun pe: 'Iyanu nla ni gbogbo ti o sọ silẹ wonyi jẹ fun mi nitoripe, mo ṣe akiyesi wipe, nṣe ni iwọ ko tilẹ le fi ara balẹ fun mi rara lati ba ọrọ mi delẹ ki o to le fesi leri ọrọ na.

"Ṣugbọn nkan ti o wa dun mọ mi ninu ọrọ na ni wipe, nṣe ni iwọ paapa kuku jẹri si ọrọ mi na ti mo nfẹ sọ fun ọ lai ti i pari rẹ, nitoripe, o ti han si mi gbangba ninu ọrọ rẹ wipe, iwọ jẹ ọkan ninu awọn ọmọ enia ti mo ntọkasi fun ọ ninu ọrọ mi wipe nwọn ko nfẹ gbọ ododo ọrọ.

"O si ti fi han mi nisisiyi pe iṣẹ kanna ti iwọ ko le ṣe ni ole-jija, bẹni awa ko ri ọna iṣẹ meji fun ọ lode aiye yi t'iwọ le fi di enia pataki bikoṣe iṣẹ ole-jija yi gan an, ṣugbọn nisisiyi, o ti sọ wipe, baba rẹ ati iya rẹ ti sọ fun ọ wipe iwọ ko gbọdọ jale, atipe, iwọ ko gbọdọ purọ, nlẹ nigbana, ọrọ na ku si ọwọ rẹ nisisiyi lati ronu jinlẹ ki o si lọ mura lati yanju ọrọ ara rẹ'.

Olotu, mo duro nihin ni ọsẹ yi, mo dupẹ o, ipade tun di ọjọ miran ọjọ rere, ọmọ-ọba nrele o, o digba.

# AKIYESI PATAKI

A fẹ ki gbogbo ẹnyin aṣoju wa ati onkawe kakiri agbaiye ma a fi irohin pataki ti o ba ṣẹlẹ ni ilu ti ẹ ngbe tabi itan aladun sọwọ si wa. Ki ẹ si gbidanwo lati ma a fi foto irohin na sọwọ si wa ki ẹnikẹni le ri idaniloju ohun ti o ṣẹlẹ na, ati aworan na ati irohin na lọfẹ ni a o tẹ jade fun nyin. Ajunmọṣe wa ko ni bajẹ o.

OLOTU


## ARADAN NERVIGORA

Oogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, iṣookun-oju, gbigbọn-ọwọ, aiiesun, adaku-ọle ati irufẹ aleebu bawọnni O jẹ ajidewe fun awọn ti o d'arugbo-eku. On ni Jagunlabi lo ti o fi di "Afẹṣẹ-ku bi ojo. A nle e bọ, o nl'ara iwaju. Akọkọluko werepe ti nso lẹhinkule ọta; b'oku s'ara ile, a ku s'ara ita".




5s. 6d. pere ni igo kan. Owo-ọkọ lọtọ.

The Egba Trading Aradan Stores
36 Denton Bridge St., P. O. Box 2, Ebute Mẹtta.




AMAMA nfun ni ni agbara

Manufactured by Glaxo Laboratories (Nigeria) Ltd., Apapa.
Trade enquiries: Glaxo-Allenburys (Nigeria) Ltd., Lagos, Aba and Kano



**Ẹnikẹni**

**ni o nra SIERA *radio***

**SIERA NI AWỌN ẸRỌ-REDIO TI O DARAJULỌ NI NAIJIRIA**

**ni tirẹ *LONI***

JOHN HOLT

Ni o npin in ti o si ntun un ṣe yika gbogbo NAIJIRIA

Awọn Onişowo Ile-Itaja:- UTC DEPARTMENT STORES, LAGOS

# Oloye Akintọla şi ile işẹ

Lati oju ewe kini

ati işẹ-owọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria jẹ ọkan ninu awọn Ikọ pẹlu Alaga orişirişi awọn Alakoso Ile-işẹ Owo Ajumọşepọ Ipinlẹ Iwọ-Orun ti nwọn lọ şe ibẹwo Olu-ibudo Ile işẹ Pepsi-Cola ni ilu New York ni Amẹrika ninu oşu kẹjọ ọdun 1959.

"Awọn Igbimọ 'Mushin Industrial Estate' ni o pese ilẹ ti nwọn fi kọ ile-işẹ na, Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun si tun ibẹ şe fun idasilẹ owo pẹẹpẹẹpẹ. Awọn Ẹgbẹ NIGERSOL ti o sişẹ ile-kiko, ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ọgọta ninu ọgọrun ipin okowo işẹ wọn ni o kọ ile-işẹ na.

"Ni oşu kẹta ọdun yi ni nwọn bẹresi kọ Ile-işẹ na, ni oşu kẹjọ ọdun yi ni ile işẹ na si bẹrẹ işẹ, eyi fi han pe awọn oşişẹ ti o kọle na jafara. Awọn ẹrọ ile-işẹ na nşe adọta-ọkẹ apoti (1,000,000 cases) ọti-aladun larin wakati-mejọ. Ọọdun ọjọ ni nwọn si fi nşişẹ ninu ile-işẹ na ni ọdun kan.

"Ẹrọ ti o nşe omi-gbigbona wa ninu Ile-işẹ na, on ni o nşe ooru omi ti o nşe ọti Pepsi-Cola ati Mirinda ti gbogbo nyin ngbadun rẹ nisisiyi. Ile işẹ na yio polowo ọja lọ si Warri, Ibini, Ijẹbu, Agbadarigi ati Ikẹja, yio si pin ọja yika Eko. Pepsi-Cola ni ẹẹdẹgbẹrin (700) Ile-işẹ ni ilu Amẹrika, o si tun ni ọọdun ile işẹ larin awọn ilu mejidilọgọrin yika gbogbo aiye, nwọn si ni awọn alamojuto işẹ fun ile-işẹ mejeji ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun.

"Nwọn ni awọn Alamojuto Işẹ, Alamojuto awọn oşişẹ ati alamojuto-owo ti awọn ọmọ Naijiria ti o nkọşẹ labẹ wọn yio gba ipo fun wọn, nwọn si nşe iranlọwọ lati polowo, lati gba oşişẹ ati lati tete ta ọja.

Ni ilu Amẹrika ni nwọn ti npọn ọti "Pepsi-Cola" ati "Mirinda" laipe, a o ma a a pọn ọn ni Ile-işẹ LAFIA CANNING FACTORY ti o le lo awọn eelo-ọti: obi-gbanja ati orombo. Şişi ile-işẹ yi şi ọna miran silẹ fun ajumọşepọ ilu Amẹrika ati Iwọ-Orun Naijiria a si nfi oju sọna fun iranlọwọ miran lati ọdọ awọn ilu okere ki işe lati ọdọ Amẹrika nikan. A si ro pe nwọn ko ni ja wa tilẹ.

"Nitorina, mo fi tayọtayọ şi Ile-işẹ Ọti-Aladun PEPSI-COLA yi."

## Ọkọ Reluwe pa iya arugbo kan

KUMASI, GHANA.

IYA arugbo kan ti orukọ rẹ njẹ Gogo Abakẹ kan agbako ọkọ Reluwe ni ilu Kumasi, Ghana, ni ọjọ Ẹti ti işe ọjọ keji oşu kẹsan ọdun yi, o si ku bamubamu. Iya arugbo yinrekọja lori irin Reluwe lojiji, şugbọn ki o to de odi keji, Reluwe timbọ pẹlu are nla ti kan an l'ara, o si gori rẹ.

Ẹru ba gbogbo awọn ti nwọn wa ni agbegbe ibẹ, kia ni nwọn si ti ranşẹ si awọn ẹbi iya yi. Iya na jẹ oninu're, o si jẹ gbajumọ enia.

Awọn Ọgbẹni Buraimọ atanda ati Alfa Balogun şe isinku iya na daradara. Oluwa ko ni jẹki a ri akufa mọ o.



Aworan oke yi ni ti awọn ibẹta ti Ọlọrun fi ta Ọgbẹni J. L. Ojo ati iyawo rẹ lọrẹ ni ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ kẹfa oşu yi ni ile wọn ni 13, Tapa St. Ebute Mẹtta. Ọgbẹni Ojo jẹ ọmọ Ibini.

## Oloye Eletu Odibo ku

EKO.

NI ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kejilelogun oşu yi ni Oloye Amusa Gbadesere Ọgabi, Eletu Odibo jalaisi si Iga rẹ l'Eko nigbati o di ẹni ọdun marundinladọrin (65 years), nwọn si sin oku rẹ ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kẹtalelogun oşu kanna si itẹ Ikoyi.

Ẹsẹ awọn aşoju Ọba Eko; awọn Oloye Asajọn-Ọlọja Ẹreko; Ọjọn; Olumẹgbọn, Ọbanikoro; Onitana; Onisẹmọ; Ọlọtọ; Saba; Aşọgbọn; Ajanaku Arẹ; Awo Oşugbo; awo Akala; awo Ọpa ati awọn enia ja nkan ja nkan miran ni o pe şọşọ si ibi aşeyẹ isinku na.

Ni ipari oşu keji ọdun 1950 ni ologbe na jẹ oye. Gẹgẹbi ipo oye idile rẹ, on ni o gbe ade le Ọba Adele Keji lori ni Ọwa, ni ọjọ kini oşu kẹwa ọdun 1949. Ologbe na fi aya mẹrin ati ọmọ mẹwa si aiye lọ.




## Ara-hihun, ara jijoni ati ara-gigenijẹ ti AWỌ-ARA TI KO DARA

Ni egbogi titun ti awọn ara Amẹrika şeşe fi ọgbọn ijinlẹ wari ti o tete ngbogunti aisan Ekuru, Rorẹ, Lapalapa, ara-sisu ati awọn aisan awọ-ara miran.

NIXODERM jẹ egbogi apolu pataki olorişi oogun mẹje ti o jẹ ipara funfun ti o nyara ba aleebu awọ-ara ja bi Ekuru, Rorẹ, Ara-sisu, Lapalapa, Ogodo, eela-Olorontọ, Oowo-imu Awọ-ori-şişi, Kokoro-jẹrun-jẹrun ati Işaka-ẹsẹ. NIXODERM nşişẹ ni kiakia a si da ara-hihun duro larin işẹju mẹje. O le ri agbayanu iyipada lẹhin ọjọ kini ti o ba lo o. Şa fi pa oju ibiti o ndun ọ ni awọ-ara ki o to lọ sun. Tiripẹpẹ ni yio dimọ ibẹ gẹgẹbi ibọwọ-afẹẹri a si ma a nşişẹ nigbati iwọ ba nsun. Nigbati o ba dide ni ọjọ keji, wa a ri i pe awọ-ara rẹ ti mọkadara, a di akọtun, a jọlọ, a si mulọ-mulọ. Larin ọjọ diẹ,




enu yio ya awọn ọrẹ rẹ si iyipada na.

Mase jẹki idaamu mu o padanu awọn ọrẹ rẹ nipa pe o ni awọ-ara buruku. Lo NIXODERM loni ki o si ri bi gbajumọ rẹ yio ti tubọ ga si. NIXODERM ntete yara sişe nitoripe o mba awọn oniruru kokoro ti o nda awọ-ara laamu ja a si pa gbogbo wọn. Ra NIXODERM ni Ile Ẹgbogi adugbo rẹ loni. O gbọdọ ni itẹlorun pẹlu rẹ, bibẹkọ, a ti aşeri lati da owo rẹ pada.

**NIXODERM**

Published by Allied newspapers Limited, Elephant House, 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited. Fun owo "IROHIN YORUBA" ọdun kan—Eko sile mejọ ati kobọ mejọ (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile mẹtala (13s.) Olotu S. M. Ademuyiwa, 2, Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.